# AARỌNI ATI KRISTI

## Ẹksodu 28:1-5; Lefitiku 8:1-36; 9:7-24;

### Heberu 7:11-28; 8:1, 2

### ẸKỌ 84 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitorina o si le gba wọn là pẹlu titi de opin, ẹniti o ba tọ̀ Ọlọrun wá nipasẹ rẹ̀, nitoriti o mbẹ lãye titi lai lati mã bẹ̀bẹ̀ fun wọn" (Heberu 7:25).**

**I A ya Aarọni ati awọn Ọmọ rẹ̀ sọtọ fun Iṣẹ Alufaa**

1. OLUWA paṣẹ ki a dá ẹwu mimọ́ ti yoo ṣe apẹẹrẹ ọ̀ṣọ́ ti ẹmi ti awọn alufaa ni lati ni, Ẹksodu 28:1-5; Ifihan 19:8
2. Ẹbọ ẹ̀ṣẹ jẹ́ ami iyasi mimọ́ ti Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ fun ipò alufaa, Lefitiku 8:1-17; 2 Kronika 5:11; Heberu 13:11-13
3. Ẹbọ sisun jẹ́ ami ifi ara wọn fun Oluwa bi ẹbọ oloorun didùn, Lefitiku 8:18-21; Ẹksodu 29:18
4. Àgbò iyasi mimọ́ ati wíwà ninu Agọ wọn fun ọjọ meje, jẹ́ ami yiya ara wọn sọtọ patapata fun iṣẹ́-isin, Lefitiku 8:22-36; Heberu 7:28

**II Aarọni ati awọn Ọmọ Rẹ̀ bẹrẹ Iṣẹ́ Alufaa**

5. A paṣẹ fun Aarọni olori alufaa lati rú awọn ẹbọ fun ara rẹ̀ ati fun awọn eniyan, gẹgẹ bi etutu, Lefitiku 9:6, 7; Heberu 7:26, 27
6. Ẹbọ wọnni ti o rú, gẹgẹ bi aṣẹ, jẹ́ ẹbọ owurọ, Lefitiku 9:8-21 (ẹsẹ 17); Ẹksodu 29:38, 39; Heberu 7:27
7. Aarọni sure fun awọn eniyan; OLUWA fi ara hàn; iná sọkalẹ; awọn eniyan si hó, Lefitiku 9:6, 22-24

**III A Fi Ipò Oyè Alufaa ti Aarọni Wé Ipò Oyè Alufaa ti Kristi**

8. Pipé – (aini-abuku) kò ti ipasẹ ipò oyè alufaa Aarọni wá bi kò ṣe lati ipasẹ ipò oyè alufaa ti Mẹlkisedeki, Heberu 7:11; Orin Dafidi 110:4
9. Ilana titun kan nipa ipò alufaa jade wá nipasẹ Kristi, Ẹni ti O wá lati inu ẹya Juda, Heberu 7:12-14; Romu 1: 3, 4
10. A yan alufaa yii, ki i ṣe gẹgẹ bi eto nipa ti ara, bi ko ṣe nipa agbara ti iyè ailopin, Heberu 7:15-17, 23, 24, 1-3
11. Ofin kò sọ ohunkohun di pipe, ṣugbọn ifihan ireti ti o dára jù lọ ṣe aṣepé, Heberu 7:18, 19, 25; Romu 8:3, 4
12. Ọlọrun tikara Rẹ̀, nipa ibura, fi idi ilana oyè alufaa titun mulẹ, Heberu 7:20-22; Orin Dafidi 110:4

## ALAYE

**Imurasilẹ awọn Alufaa**

Gbogbo itọni ti a fi lé Mose lọwọ fun imurasilẹ Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ fun iṣẹ iranṣẹ wọn gẹgẹ bi alufaa fi hàn bi iṣẹ naa ti wuwo to ti awọn ti a fi jẹ oyè alufaa lati ọwọ́ Ọlọrun ni lati ṣe. Iṣẹ awọn alufaa ni lati maa fi ara hàn niwaju Ọlọrun nitori awọn Ọmọ Israẹli. Aṣọ ti wọn n wọ̀ jẹ́ apẹẹrẹ amuyẹ ti ẹmi eyi ti awọn alufaa gbọdọ ni ki wọn ba le yẹ fun ipò naa. Ẹbọ ati ọrẹ ti wọn mú wá sori pẹpẹ idẹ jẹ́ apẹẹrẹ Ẹjẹ ti wọ́n gbọdọ ta silẹ ati etutu ti wọn gbọdọ ṣe fun ara wọn ati fun gbogbo eniyan; ọrẹ wọn duro fun idalare wọn, isọdimimọ́ wọn, ati ifararubọ fun wọn Oluwa, gbogbo eyi ti Ọlọrun ti ṣe ipese fun ni kikún labẹ Ofin. Bi o tilẹ jẹ pe awọn nnkan wọnyii kò ni agbara kankan ninu ara wọn lati sọ awọn ti n wá si ibi irubọ naa di pipé (Heberu 10:1), sibẹ, nitori ti ohun ti wọn jẹ́ ojiji fun, awọn eto ati ilana isin inu agọ naa patapata jẹ apẹẹrẹ pipe; bakan naa ni wọn jẹ igbekalẹ ti o péye perepere fun irapada awọn Ọmọ Israẹli lati bá OLUWA rìn, ni mimọ́ iwa ati ni ododo ni ọjọ ayé wọn gbogbo ki wọn ki o le jẹ iṣura fun Un, ijọba alufaa ati orilẹ-ède mimọ (Ẹksodu 19:5, 6).

**A fi Aarọni jẹ Olori Alufaa**

Ọlọrun ni o fi Aarọni funra rẹ̀ jẹ oye olori alufaa; apa kan aṣọ ti o n wọ̀ jẹ igbaya idajọ ti wọn ṣe ni iṣẹ ọna daradara, pẹlu wura ati aṣọ alaro, ati elese aluko ati òdòdó ati ọgbọ olokun wiwẹ, pẹlu okuta iyebiye mejila, lara eyi ti a kọ orukọ ẹya Israẹli mejila sí. Nigba ti Aarọni bá si wá siwaju OLUWA, oun a wá pẹlu orukọ wọnyii ni ejika rẹ̀ (Ẹksodu 28:12). Ṣugbọn ohun ti Aarọni ni lati ṣe ju kiki aṣọ wiwọ̀ lọ. A kọ ọ silẹ pe "Iwọ o si fi Urimu on Tummimu sinu igbàiya idajọ; nwọn o si wà li àiya Aarọni, nigbati o ba nwọle lọ niwaju OLUWA; Aarọni yio si ma rù idajọ awọn ọmọ Israẹli li àiya rẹ̀ nigbagbogbo niwaju OLUWA" (Ẹksodu 28:30).

**Ikuna awọn Alufaa ati awọn Eniyan naa**

Ṣugbọn ọpọlọpọ ninu awọn alufaa ni wọn kuna ipe giga wọn, awọn eniyan si padanu ibukun nla ti i ba jẹ ti wọn labẹ Ofin paapaa. Nipa ti ode ara, wọn pa ohun gbogbo ti wọn kọ sinu ofin Mose mọ́ kinnikinni, ṣugbọn otitọ ti ó wà ninu rẹ̀ kò de inu ọkàn wọn (Orin Dafidi 51:6), isin wọn si jẹ ti ode ara lasan, omulẹ mofo patapata. Nitori isin ti ode ara yii ni OLUWA ṣe ti ẹnu Wolii Isaiah ba wọn wi pe, "OLUWA ni, kini ọ̀pọlọpọ ẹbọ nyin jasi fun mi? emi kún fun ọrẹ sisun agbò, ati fun ọrá ẹran abọ́pa; bẽni emi kò si ni inu didùn si ẹjẹ akọ malũ, tabi si ti ọdọ-agutan, tabi si ti obúkọ. Nigba ti ẹnyin wá lati fi ara hàn niwaju mi, tali o bere eyi lọwọ nyin, lati tẹ̀ agbalá mi? Ẹ má mu ọrẹ asan wá mọ́: turari jasi ohun irira fun mi; oṣù titun ati ọjọ isimi, ìpe ajọ, emi kò le rọju gbà; ẹ̀ṣẹ ni, ani apèjọ ọ̀wọ nì. Oṣù titun nyin ati ajọ ìdasilẹ nyin, ọkàn mi korira; nwọn jasi iyọlẹnu fun mi; o sú mi lati gbà wọn. Nigba ti ẹnyin si nà ọwọ́ nyin jade, emi o pa oju mi mọ fun nyin: nitõtọ, nigbati ẹnyin ba gbà adura pupọ̀, emi ki yio gbọ́: ọwọ́

nyin kun fun ẹ̀jẹ” (Isaiah 1:11-15). Oluwa, ni ọjọ igba ni, gẹgẹ bi lọjọ oni, n fẹ ohun kan ti o tayọ aṣehan ati isin ode ara lásán làsàn. O paṣẹ bayii pe: |Ẹ wẹ̀, ki ẹ mọ́; mu buburu iṣe nyin kuro niwaju oju mi” (Isaiah 1:16).

Igbekalẹ iṣẹ iranṣẹ alufaa, aṣọ oniṣẹ ọnà daradara fun wiwọ, ẹbọ ori pẹpẹ, turari ti wọn n sun lori pẹpẹ wura, Ibi Mimọ́ Julọ ti ó wà lẹyin aṣọ ikele, ibi ti olori alufaa maa n wọ̀ lẹẹkan ṣoṣo lọdun pẹlu ẹjẹ akọ maluu ti wọn pa nitori ẹṣẹ ti ara rẹ̀ ati ẹjẹ ewurẹ nitori ẹṣẹ awọn eniyan – gbogbo wọnyii ni Ọlọrun pa laṣẹ ninu Ofin Mose; ṣugbọn apẹẹrẹ ati ojiji ohun rere ti n bọ̀ ni wọn jẹ́. Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli si ti mu oju wọn kuro lara Ẹni naa ti apẹẹrẹ ati ojiji n tọka si, wọn ti padanu ohun gbogbo. “Nibiti iran-woli kò si, enia a yapa” (Owe 29:18).

**Ipò Olori Alufaa ti Kristi**

Gẹgẹ bi ohun gbogbo ti o jẹ mọ isin agọ ti tọka si Kristi, bẹẹ ni awọn wolii naa pẹlu tọka si I. Mose sọ asọtẹlẹ nipa Kristi gẹgẹ bi Wolii ti n bọ̀ nigba ti o sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe, “OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé wolĩ kan dide fun ọ lãrin rẹ, ninu awọn arakọnrin rẹ, bi emi, on ni ki ẹnyin ki o fetisi” (Deuteronomi 18:15). Oun ni wolii Jeremiah n tọka si gẹgẹ bi Ọba lori itẹ Dafidi, nigba ti o kọwe bayii pe, “Sa wò o, ọjọ mbọ, li OLUWA wi, ti emi o gbe Ẹka ododo soke fun Dafidi, yio si jẹ Ọba, yio si ṣe rere, yio si ṣe idajọ ati ododo ni ilẹ na” (Jeremiah 23:5). Dafidi Onisaamu pẹlu kọwe nipa Rẹ̀ gẹgẹ bi Olori Alufaa ti ipò Rẹ̀ yatọ patapata: “OLUWA ti bura, ki yio si yi ọkàn pada pe, Iwọ li alufa titi lai nipa ẹsẹ ti Mẹlkisedeki” (Orin Dafidi 110:4). Bayii ni a sọ asọtẹlẹ nipa Jesu pe yoo wá gẹgẹ bi **Wolii, Alufaa ati Ọba.** Ni akoko iṣẹ iranṣẹ ọdun mẹta aabọ̀ ti O fi n kọ́ awọn eniyan, O lo ipò Rẹ̀ gẹgẹ bi Wolii. Lẹyin igoke re Ọrun, ti o wọ inu Agọ tootọ lọ, eyi ti a kò fi ọwọ́ kọ́, o di Olori Alufaa giga jù lọ nibi ti O gbé n bẹ̀bẹ̀ fun wa lonii. Nigba ti O ba si pada wá lati ṣe idajọ orilẹ-ède gbogbo. “OLUWA yio si jọba lori gbogbo aiye” (Sekariah 14:9).

**Alufaa Nipa Ẹsẹ Mẹlkisedeki**

Paulu Apọsteli ti ṣe alaye fun ni pataki iṣẹ iranṣẹ Kristi gẹgẹ bi Olori Alufaa “nipa ẹsẹ Mẹlkisedeki” (Heberu 7:1-28). Niti pe Mẹlkisedeki alufaa Ọga-ogo ju lọ, gba idamẹwa lọwọ Abrahamu, o ni ipo ti o ga ju ipo baba igbagbọ́ paapaa lọ, bakan naa, o si tun ga ju oye alufaa ti ẹya Lefi eyi ti awọn iran Abrahamu gbà. “Njẹ ibaṣepe pipé mbẹ nipa oyè alufa Lefi, (nitoripe labẹ rẹ̀ li awọn enia gbà ofin), kili o si tún kù mọ́ ti alufa miran iba fi dide nipa ẹsẹ Mẹlkisedeki, ti a kò si wi pe nipa ẹsẹ Aarọni?” (Heberu 7:11). Ipo oye alufa ti Aarọni kò pe. Aarọni ati awọn iran rẹ̀ jẹ́ ẹni kikú, wọn si jẹ ojiji Olori Alufaa giga “eyiti a kò fi jẹ gẹgẹ bi ofin ilana nipa ti ara, bikoṣe nipa agbara ti iye ailopin” (Heberu 7:16). Bi Majẹmu Titun ti n dé ti Majẹmu Laelae si n kọja lọ, (Heberu 8:13), bakan naa Olori Alufaa wa giga ju lọ ti rọ́pò gbogbo ilana oye alufaa ti Aarọni, eyi ti o ti rekọja lọ pẹlu gbogbo apẹẹrẹ ati ojiji. Nitori naa kò tun si ipo alufaa kankan mọ́ laaarin ijọ gẹgẹ bi ilana eniyan. Awọn ijọ ẹlẹsin ti ọjọ oni ti wọn si n tẹle eto oye alufaa gẹgẹ bi igbekalẹ ilana ofin nipa ti ara, n ṣe lodi si ẹkọ Ọrọ Ọlọrun ti o hàn gbangba. Kristi ni Olori Alufaa wa, Ẹni ti O “de bi Olori Alufa awọn ohun rere ti mbọ̀, nipasẹ agọ́ ti o tobi ti o si pé ju ti iṣaju, eyiti a kò fi ọwọ́ pa, eyini ni, ti ki iṣe ti ẹ̀da yi. Bẹ̃ni ki iṣe nipasẹ ẹ̀jẹ ewurẹ ati ọmọ malu, ṣugbọn nipa ẹjẹ on tikararẹ̀ o wọ ibi mimọ lẹ̃kanṣoṣo, lẹhin ti o ti ri idande ainipẹkun gbà fun wa” (Heberu 9:11, 12). “Nitorina o si le gba wọn là pẹlu titi de opin, ẹniti o ba tọ̀ Ọlọrun wá nipasẹ rẹ̀, nitoriti o mbẹ lãye titi lai lati mã bẹ̀bẹ fun wọn” (Heberu 7:25).

Lẹẹkan lọdun ni Ọjọ Etutu olori alufaa pẹlu ẹ̀jẹ ewurẹ, maa n wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ nitori awọn eniyan ti wọn yoo duro lode tọwọtọwọ ninu ijọsin fun Ọlọrun wọn a si maa reti ipadabọ olori alufaa. Bakan naa ni Olori Alufaa wa ti wọ Ibi Mimọ́ Julọ lọ lẹẹkan ṣoṣo, ki i ṣe pẹlu ẹjẹ obukọ tabi ti ewurẹ, ṣugbọn pẹlu Ẹjẹ iyebiye ti Oun tikara Rẹ̀ lati bẹbẹ fun wa; nigba ti awa ti a jẹ́ ọmọ-ẹyin Rẹ̀ tootọ n duro lode ti a si n foju sọna pẹlu ayọ ti a n reti ipadabọ Rẹ̀. O n mura nisisiyii lati fi itẹ aanu Rẹ̀ silẹ ki O si pada wá si ayé lati mú Iyawo Rẹ̀ ti n wọna fun bibọ Rẹ̀ lọ sọdọ ara Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Nitori ki ni a ṣe fi awọn alufaa Majẹmu Laelae jẹ?
2. Ki ni iṣẹ wọn nipa ti isin agọ?
3. Njẹ pipa akọ maluu fun isọdimimọ́ Aarọni sọ ọ di mimọ́ tabi aṣa lasan ni?
4. Ki ni ṣe ti Ọlọrun kọ irubọ ati ipade isin ni akoko Isaiah? (Isaiah 1:11-15)
5. Awọn oyè mẹta wo ni a ti lana rẹ pe Kristi ni lati jẹ? Ṣe alaye bi O ti dí awọn oyè naa.
6. Lọna bawo, ati nigba wo si ni O gba ipò oyè Olori Alufaa?
7. Lọna wo ni ipò oyè alufaa ti Kristi fi yatọ si ti Aarọni?
8. Nigba ti Kristi ba fi itẹ Rẹ̀ bi alagbawi silẹ, ipò oyè wo ni yoo tun wà?